# NÍPA ÒǸKỌ̀WÉ



Ọmọ bíbí ìlú Abẹ́òkúta ni Solomon Olúfẹ́wọ́jú Mákindé. Ó ka ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní Salvation Army Primary School, Arárọ̀mí Ládipọ̀ àti African Church Primary School Adéwùsì lẹ́bàá Abẹ́òkúta.

Ilé ẹ̀kọ́ St. Joseph Secondary Commercial School ni ó tún lọ ní ìlú Agége. Lẹ́yìn náà ó gba ìwé ẹ̀rí Olùkọ́ni onípò kejì láti ilé ẹ̀kọ́ Ansar - Ud - Deen Teacher's College, Ọ̀fà. Ó gba oyè B. A. Ed. ní Yunifásítì Ìpínlẹ̀ Ògùn àti oyè M. Ed. lórí ẹ̀kọ́ èdè láti ilé - ẹ̀kọ́ gíga Yunifásítì Ìbàdàn.

Ó ṣiṣẹ́ ní àwọn ilé - ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti sẹ́kọ́ńdìrì ní ìpínlẹ̀ Ògùn. Ó tún ṣiṣẹ́ ní Federal Government Girls College Ọ̀yọ́ àti Federal Government College Ògbómọ̀ṣọ́ gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ àgbà nínú èdè Yorùbá.

Ní ọdún 1996, ó ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí Olùkọ́ èdè Yorùbá ní Federal College of Education (Special) Ọ̀yọ́. Ní báyìí, Olùkọ́ ni ní Yunifásítì Ìpínlẹ̀ Èkó ní Curriculum Studies Department (Language Unit).

ISBN 978 - 027 - 485 - 5

# Ọgbọ́n Ìkọ́nilédè YORÙBÁ

## ÌWÉ ÌLÉWỌ́ FÚN ÀWỌN OLÙKỌ́

LANRE MAKINDE

# ỌGBỌ́N ÌKỌ́NILÉDÈ YORÙBÁ

IWE ÌLÉWỌ FÚN AWỌN OLÙKỌ́

Láti Ọwọ́

**LANRE MAKINDE**

Lecturer (Language Unit)
Department of Curriculum Studies
Faculty of Education
Lagos State University

©Lanre Makinde 1997
All rights reserved. No part of
this publication may be reproduced or
transmitted, in any form or by any
means, without permission.

First Published 1997

ISBN 978 - 027 - 485 - 5

*Published by:* ZIKLAG EDUCATIONAL PUBLISHER
P. O. Box 4097 Festac town, Lagos. Nigeria

*Printed by:* KALOST VENTURES LTD.
Lagos. Nigeria. Tel: 5890256

# ÌFISORÍ

*Mo fi ìwé yìí júbà Olúwa Ọlọ́run Olódùmarè,*
*Ẹni tí gbogbo agbára lọ́wọ́ àti lọ́run;*
*lókè àti nílẹ̀; lókun àti lọ́gbun*
*gbogbo ń bẹ ní ìkáwọ́ Rẹ̀.*

# ÌTỌ́KA ÀKỌ́ỌNÚ


| | | PAGE |
|---|---|---|
| ỌRỌ̀ ÌSÁÁJÚ | | VI |
| Orí kì-ín-ní | Kí ni Èdè | 1 |
| Orí kejì | Ìdí tí A ṣe Ń fi Èdè Yorùbá kọ́ ọmọ | 16 |
| Orí kẹta | Èdè gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ | 19 |
| Orí kẹrin | Ìmọ̀ọse Nínú Èdè | 23 |
| Orí karùn-ún | Bí ọmọ ṣe ń gba Èdè Abínibí | 33 |
| Orí kẹfà | Àwọn Tíọ́rì-ọgbọ́n Ìkọ́ni Ajẹmédè | 36 |
| Orí keje | Àgbéyẹ̀wò kọ̀rìkúlọ̀ọmù Yorùbá | 59 |
| Orí kẹjọ | Bí a ṣe lè kọ́ Àwọn Èka Iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan | 61 |
| Orí Kẹsàn-án | Àwọn ohun Èlò Akọ́mọyémọ | 71 |
| Orí kẹ́wàá | Ṣíṣe Àyẹ̀wò Tàbí Ìgbéléwọ̀n Iṣẹ́ Akẹ́kọ̀ọ́ | 73 |
| Orí Kọkànlá | Àwọn Ìṣoro tí ó ń dojú kọ ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá | 81 |
| Àwọn Ìbéèrè fún Ìdánrawò | | 88 |
| Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí | | 89 |

## ỌRỌ ÌṢAÁJÚ

Bí ọdún ti ń yí lu ọdún ni ìdàgbàsókè ń dé bá ẹ̀kọ́, tí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ sì ń peléke síwájú àti síwájú. Iṣẹ́ ìwádìí sì ń fi hàn pé kèrééémí kọ́ ni ipa tí èdè àbínibí ń kó nínú ẹ̀kọ́ ọmọ. Nítorí ìdí èyí, o yẹ kí gbogbo olùkọ́ ó mọ̀ pé ìpèníjà ńlá ló ń bẹ níwájú. Olùkọ́ èdè Yorùbá kò gbọdọ̀ rẹ̀yìn láti mú ìdàgbàsókè bá ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá nípa ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ nínú iṣẹ ẹ̀rọ.

Àwọn oyin parapọ̀, wọ́n ṣe afárá.àwọn ikán náà sì parapọ̀, wọ́n molé. Àwọn orílẹ̀ èdè bí i Rọ́ṣíà àti Jẹ̀páànì parapọ̀, wọ́n fèdè tiwọn kẹ́kọ̀ọ́, wọ́n sì ń gbé ǹǹkan ńlánlá ṣe nílẹ̀ tiwọn. Kò yẹ kí ọmọ Yorùbá ó rò pé èdè tòun kò wúlò fún ìdàgbàsókè. Tẹ̀ni ni tẹ̀ni ohun tí ó wà lẹ́mìíí òǹkọ̀wé yìí ni pé ó tọ́ ó sì yẹ kí a máa fi èdè àbínibí kọ́ gbogbo iṣẹ́ láti ilé ẹ̀kọ́ jẹ́lé-ó-simi títí fi dé Yunifásítì.

Ìtọ́wò ọbẹ̀ ni ìwé ìléwọ́ yìí jẹ́. Nínú rẹ̀ ni a ti mú ẹnu ba díẹ̀ nínú àwọn tíọ́rì àti ìlànà tí a lò ọ̀àmúlò fún kíkọ́ èdè Yorùbá yálà gẹ́gẹ́ bí èdè àbínibí tàbí èdè àkọ́kúntẹ̀ni. Òǹkọ̀wé kò sọ pé òun ti dé òpin ìmọ̀ nípa àwọn tíọ́rì àti ìlànà wọ̀nyí. Ìpèníjà ni èyí yẹ kí ó jẹ fún gbogbo Olùkọ́ èdè yìí. Kí a pèsè ohun èlò fún iṣẹ́ takuntakun tí ó ń bẹ níwájú wa.

Mo fi àkókò yìí dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n, ọ̀mọ̀wé, òǹkọ̀wé àti àwọn olùkọ́ tí wọn ti kọ́ mi ní iṣẹ́. N kò ní ṣàìdúpẹ́ lọ́wọ́ Alàgbà Ọmọníyì Kayọ̀dé ti Federal College of Education (Special), Ọ̀yọ́ fún ìtọ́ni tí mo ní lọ́dọ̀ wọn. Mo tún dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọ̀mọ̀wé Bíọ́dún Akínpẹ̀lú ẹni tí ìmọ̀ rẹ̀ nínú èdè Yorùbá àti Ọgbọ́n ìfẹ̀rọkédè kó ipa tó jọjú nínú ìgbésí ayé mi gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ èdè Yorùbá. Mo sì tún dúpẹ́ lọ́wọ́ Alàgbà àti Ẹni ọ̀wọ̀ B. A. Adélọlá ti wọn pèsè oríṣìíríṣìí ìwé fún mi láti kà lórí iṣẹ́ yìí. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọ̀jọ̀gbọ́n Babátúndé Bashir Ọdẹ́rìndé tí wọ́n ń gún mi ní kẹ́sẹ́ ìmọ̀ láti kọ̀wé. Ọ̀gbẹ́ni Samuel Afọlábí, Afínjú Òǹtẹ̀wé - O ṣeun púpọ̀.

Ọpọ̀ àwọn ẹni bí ẹni àti ènìyàn bí ènìyàn ni mo jẹ ní gbèsè ọpẹ́ tí n kò ní lè dárúkọ tán sí inú ìwé yìí. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ ìyàwó mi Wùmí àti Olúṣẹ́gun ọmọ Jésù fún ìfọwọ́sowọ́pọ̀ wọn láti jẹ́ kí iṣẹ́ ìwé yìí ó ṣe é ṣe. Ẹ ṣeun púpọ̀

*Solomon Olúírewájú Mákinde*
1997.



# ORÍ KÌ-ÍN-NÍ

## KÍ NI ÈDÈ?

Èdè jẹ́ ọ̀nà kan tí a ń gbà láti gbé èrò, ìfẹ́ inú ẹni tàbí ẹ̀dùn ọkàn ẹni jáde ní ọ̀nà tí yóò gbà yé olùgbọ́. Èdè síso àti èdè kíkọ jẹ́ àǹfààní kan pàtàkì tí ọmọ ènìyàn fi ṣẹ̀gbọ́n gbogbo àwọn ẹ̀dá yòókù tí Olódùmarè, Ẹlẹ́dàá dá sórí ilẹ̀ ayé.

Lóòótọ́ ni àwọn ẹ̀dá yòókù ní ọ̀nà tí wọ́n ń gbà bá ara wọn "sọ̀rọ̀", bí àpẹẹrẹ, igbe ẹranko kan a máa ní ìtumọ̀ sí ẹranko mìíràn onírú tirẹ̀, kíké aparò kò ṣàìyé ẹyẹ aparò ẹlẹ́gbẹ́ rẹ̀, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni kíkùn yùnmuyùnmu oyin kò ṣàìyé ìran oyin. Ṣùgbọ́n bí a bá wo "ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀" àwọn ẹ̀dá wọ̀nyí, kò sí èyí tí ó ní àmúyẹ irúfẹ̀ èyí tí èdè ènìyàn ní. Aṣọ tí aparò mú wá,sáyé ní í mú rọ̀run. "Èdè" àwọn ẹ̀dá wọ̀nyí tàbí kí a kúkú pè é ní "àmì ìbánisọ̀rọ̀" kì í dàgbà. Ọ̀rọ̀ àyálọ̀ kò sí nínú ẹ̀dè tiwọn, èyí tí a ti dá mọ́ wọn nìkan náà ni wọ́n ń mú lò.

Àwọn ọ̀nà mìíràn wà tí ọmọ ènìyàn máa ń gbà láti bá ẹnìkejì rẹ̀ sọ̀rọ̀, yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀ ẹnu. A lè lo ara láti bá ènìyàn sọ̀rọ̀. Bí a bá mi gbogbo ara nígbà mìíràn, o lè túmọ̀ sí pé a kò gba ohun tí ẹnìkan gbé wá síwájú wa. A lè lo orí láti sọ ọ̀rọ̀. A lè fi orí jọ́nẹ̀n sí ọ̀rọ̀ kan, a sì lè fi takò ó. A lè fi ojú bá ènìyàn sọ̀rọ̀ láti bẹ̀ ẹ́, láti fi ìfẹ́ hàn sí i (pẹ̀lú ẹ̀dọ̀ ojú), láti kìlọ̀ fún ènìyan, láti lé e tàbí láti bú u. A lè fi ojú fa aṣọ ẹlòmíràn ya. Ènìyàn sì le lo ìfé sísú.

A lè fi ọwọ́ sọ ẹgbàágbèje ọ̀rọ̀. Àwọn odi kò ní ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ mìíràn tí ó gúnmọ́ ju ọwọ́ lọ. Láyé ọjọ́un àná àti lóde òní, àwọn Yorùbá a máa fi ìlù bá ara wọn sọ̀rọ̀. Ọ̀na ìbánisọ̀rọ̀ "ńlá" ni ìlù jẹ́ lọ́wọ́ àyàn. Ṣebí àyàn ló fi ìlù sọ pé:

Ẹ fà wọ́n nírùngbọ̀n tu,
Ẹ fà wọ́n nírùngbọ̀n tu,
Ẹni tí ò lówó lọ́wọ́ tó ń aárùngbọ̀n sí
Ẹ fà wọ́n nírùngbọ̀n tu.

Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, Yorùbá le pa àrokò ránṣẹ́ sí ènìyàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀. Bí àpẹẹrẹ, bí ènìyàn méjì bá ń jà tí alàgbà kan bá sì fi ìlà rẹ̀ ránṣẹ́ sí wọn ohun tí ẹyí túmọ̀ sí ni pé òun fi orí òun bẹ̀ wọ́n kí wọn jẹ́ kí ìjà náà ó parí. Orísìírísìí ni ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí kò la ọ̀rọ̀ ẹnu lọ. Ṣùgbọ́n gbogbo àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ kò ní ànfààní àti àmúyẹ láti gbé èrò ọkàn ẹni jáde ní kíkún.

Yorùbá Gẹ́gẹ́ bí Èdè.

Kò sí ẹni tí ó lè fi ọwọ́ sọ̀yà pé òun mọ bí a ti ṣèdá orúkọ Yorùbá. Iṣẹ́ ọpọlọ àti èrò mímú ni àwọn ènìyàn ń gbé kalẹ̀. Orírun Yorùbá gan-an, ọ̀rọ̀ àríyànjiyàn ni.
Púpọ̀ nínú àwọn òǹkọ̀wé ni wọ́n ti èrò tiwọn hàn. Johnson (1921) sọ pé láti ilẹ̀ Mẹ́kà ni Yorùbá ti ṣí wá yàtọ̀ sí àwọn Èkìtì. Lucas (1949:37) sọ pé láti ìhà Àríwá Egíbítì ni Ìran Yorùbá ti ṣí wá sí ìhà Gúsù Egíbítì, láti ibẹ̀ ni wọ́n ti wá sí Sùdáànì (Sudan) títí wọ́n fi dé ibi tí a mọ̀ wọ́n mọ́ lónìí. Ọjọ̀gbọ́n Bíóbákú (1957) sọ pé láti agbègbè ìlà oòrùn ayé láàárín àwọn ẹ̀yà Júù àti àwọn Lárúbáwá pẹ̀lú àwọn ará ìhà Àríwá Egíbítì ni àwọn Yorùbá ti sè wá. Ó fi kún un pé ẹgbẹ́ méjì ni ìṣíkúrò náà jẹ́. Àwọn ẹgbẹ́ kìíní-ní ni àwọn Èkìtì, àwọn tí ó ti ṣí wá sí ibùgbé wọn láti nǹkan bí ọdún keje lẹ́yìn ikú Olúwa wa (7 A.D.) Àwọn ẹgbẹ́ kejì ni wọ́n tẹ̀dó sí Ilé-Ifẹ̀ nípasẹ̀ olórí wọn tí ó ń jẹ́ Odùduwà ọmọ Lámúrúdu.

Ìtàn sọ pé ìjà ẹ̀sìn ni ó lé àwọn Yorùbá kúrò ní Mẹ́kà nínú èyí tí Lámúrúdu kú sí àti pé Yaroba ọmọ Kahtan ni ẹ̀ṣù bèlèkè tí ó lé Odùduwà àti ẹbí rẹ̀ kúrò ní Mẹ́kà.

Gẹ́gẹ́ bí Ọláyẹni (1964 : 13) ti ṣàlàyé, ó ṣe é ṣe kí ìṣẹ̀dá orúkọ Yorùbá ó wáyé láti ara orúkọ Yaroba ẹni tí ó lé wọn kúrò ní Mẹ́kà



fún ohun ìrántí. Ìtàn mìíràn tún sọ pé àwọn Haúsá ni ó máa ń pe Ìran Yorùbá ní Yarìbá àti pé nígbà tí ó yá, ó di Yoòbá. A wí i lọ, a wí i bọ̀, gbogbo ọmọ Yorùbá gbà pé Ilé-Ifẹ̀ ni orísun wọn àti pé Odùduwà ni baba Yorùbá. Ẹ̀sìn àbáláyé àwọn Yorùbá sì dọ́gba bákan náà. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni èdè àti ìgbé ayé wọn lápapọ̀.

Èdè Yorùbá jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn èdè tí ó gbajúmọ̀ ní ilẹ̀ Áfíríkà. Ó jẹ́ èdè tí ó tún ní àwọn ẹ̀ka èdè (àdúgbò) tí ó fẹ́rẹ̀ tó àádọ́ta. Àwọn tí ó sì ń sọ èdè Yorùbá jákè-jádò àgbáńlá ayé kò sì lè dín ní ọ̀ọ́dúnrún - ó - lé - lẹ́gbẹ̀rún ọkẹ́ (26,000,000) Èyí tí ó jẹ́ ojúlówó èdè Yorùbá ni a fi ń ṣe ìròyìn, òun ni a fi ń kọ ìwé, òun ni a fi ń kọ́ ọmọ ní ilé-ìwé, ó sì yé gbogbo àwọn ẹ̀yà tí a mọ̀ sí Yorùbá.

Lára àwọn ibi tí a ti le rí àwọn Yorùbá ni ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, Ọ̀ṣun, Ògùn, Oǹdó, Èkìtì, Èkó, Edó, Delta, Kwara àti Kàbà. Yàtọ̀ sí pé àwọn ọmọ Yorùbá wà ní gbogbo ìpínlẹ̀ Nàìjíríà, a lè rí ògúnlọ́gọ̀ wọn ní àwọn orílẹ̀-èdè Ìwọ̀ oòrùn Áfíríkà bí i Bìnì, Tógò, Sàró, Làìbéríà, Gánà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni a tún lè rí àwọn tí ó ń sọ èdè Yorùbá ní àwọn ilẹ̀ bí i Ìwọ̀ Oòrùn Indies, Gúsù Amẹ́ríkà, Kúbà, Bùràsíìlì àti àwọn ilẹ̀ mìíràn bẹ́ẹ̀.

Lára àwọn ẹ̀ka èdè Yorùbá ni Ọ̀yọ́, Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì, Ọ̀wọ̀, Oǹdó, Ẹ̀gbá, Ìjẹ̀bú, Ìkálẹ̀, Ìlàjẹ, Ìjó-Àpọ̀i, Ìkàrẹ́, Ifẹ̀, Yàgbà, Gbẹdẹ, Àwórì, Oǹdó abbl. Lára àwọn ẹ̀ka èdè tí ó súnmọ́ èdè Yorùbá pẹ́kípẹ́kí ni Ẹ̀gùn, Èbìrà, Itsekiri abbl.

Àwọn ẹ̀yà Yorùbá tí ó ń sọ ẹ̀ka-èdè Ọ̀yọ́ ni àwọn tí ò ń gbé nínú Ọ̀yọ́, Òṣogbo, Ògbómọ̀ṣọ́, Ìwó, Ọ̀dọ̀ Ọbà, Ìbàdàn abbl, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìyàtọ̀ díẹ̀díẹ̀ wà nínú èdè àwọn ìlú wọ̀nyí. Àwọn ará òkè Ògùn tó ń sọ ẹ̀ka-èdè Oǹkò nígbà tí ó ṣe pé àwọn ará ìlú Iléṣà, Ìbòkun, Ìrẹ̀sì-Ilé, Ìdómìnàsí, Ifẹ̀wàrà, Ìjẹ̀bú-Ìjẹ̀ṣà, Ẹ̀ṣà Òkè, Ẹ̀ṣà-Ọdò máa ń sọ Ìjẹ̀ṣà.

Ẹ̀ka èdè Èkìtì sì jẹ́ ti àwọn Adó-Èkìtì, Emùré Èkìtì, Igèdè Ìrun àti àwọn apá Àríwá Àkókó. Ẹ̀gbá gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ka èdè jẹ́ ti àwọn ìlú bí i Aké, Òwu (Ẹ̀gbá), Òkè-Ọ̀nà, Kémta, Ìtẹ̀sí, Ìtokò, Ìlúgùn, Ìbarà, Ìkèrèkú, Owódé, Ọbáfẹ́mi, Wásimi, Ifọ̀, Ìtori, Ọdẹ́dá, Olókèméjì, Ẹmẹ̀rẹ̀, Ìjeun, Alápàkó, Ògúnmákin abbl. Ìjẹ̀bú gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ka èdè jẹ́ ti àwọn ará Ìjẹ̀bú - Òde, Ìjẹ̀bú - Igbó, Ìjẹ̀bu - Ìfẹ̀, Rẹ́mo, Àgọ́-Ìwòyè, Àwà, Ọrù, Ṣàgámù, abbl. Ẹ̀ka-èdè Ọ̀ndó ni a ń sọ ní àwọn ìlú bí i Ọ̀ndó, Òkè-Igbó, Ilè-Olújì abbl. tí a sì ń sọ Ọ̀wọ̀ ní àwọn ìlú bí i Ọ̀wọ̀, Ìkàrẹ́ àti Ìdànrè.

Àwọn ará Ayétòrò - Gbẹ́dẹ̀ àti Iyàn ni ó ń sọ ẹ̀ka èdè Gbẹ́dẹ̀. Àwọn tí ó ń sọ ẹ̀ka-èdè Ìkálẹ̀ ni Igbó-tako, Òde Ayé, Ìyìn - Odò, Ìgbokodá àti Òkìtìpupa. Àwọn ará Akúrẹ́ àti Ìkẹ́rẹ́ ni ó sì ń sọ Ìkàrẹ́.

## YORÙBÁ GẸ́GẸ́ BÍ ÈDÈ ÀBÍNIBÍ TÀBÍ GẸ́GẸ́ BÍ ÈDÈ KEJÌ

Ní gbogbo àgbáyé, ọ̀nà méjì ni ènìyàn fi lè gba èdè. Ọ̀nà kìn-ín-ní ni èyí tí a bí ní bí tí a mọ̀ sí èdè àbínibí àti èyí tí a gbà tàbí kọ́ láti ibòmíràn tí a mọ̀ sí èdè kejì tàbí èdè kẹta abbl.

## YORÙBÁ GẸ́GẸ́ BÍ ÈDÈ ÀBÍNIBÍ (L1).

Èdè àbínibí ni èdè náà tí a bí ọmọ sí inú rẹ̀, tí ọmọ dàgbà sí inú rẹ̀ tí ó sì ṣe bẹ́ẹ̀ di èyí tí ọmọ dàgbà sí inú rẹ̀ tí ó sì ṣe bẹ́ẹ̀ di èyí tí ọmọ ń lò nígbà gbogbo nínú èrò àti ìṣe re. Èdè yìí ni ó jẹ́ èdè àkọ́kọ́ fún ọmọ náà. (Ọlọ́pàdé 1985 : 7). Yorùbá ni èdè àbínibí àwọn ọmọ káàárọ̀ - o - ò - jíire.

Gẹ́gẹ́ bí òfin àti ètò ìjọba lórí èdè nínú ètò ẹ̀kọ́ Nàìjíríà, èdè àbínibí yìí ni a gbọ́dọ̀ fi kọ́ ọmọ ní àwọn ilé ẹ̀kọ́ - alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ fún ọdún mẹ́ta àkọ́kọ́, o sì tún jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn iṣẹ́ tí a ń ṣe ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, ilé - ẹ̀kọ́ girama, ilé-ẹ̀kọ́ gbogbo àti ní Yunifásítì.



## YORÙBÁ GẸ́GẸ́ BÍ ÈDÈ ÀKỌ́KÚNTẸ́NI (L2).

A ń kọ́ èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè àkọ́kúntẹ́ni ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ girama ọlọ́dún mẹ́ta àkọ́kọ́. Ohun tí ó pàdí èyí kò ṣẹ̀yìn ìpinnu (ìjọba) lórí èdè èyí tí ó kàn án nípá fún gbogbo ọmọ Nàìjíríà láti kọ́ èdè Nàìjíríà mìíràn (nínú èdè Ìgbò, Haúsá àti Yorùbá) mọ́ èdè rẹ̀ ní ilé-ẹ̀kọ́ girama ọlọ́dún mẹ́ta àkọ́kọ́.

Síwájú sí i, a tún ń kọ́ ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí àkọ́kúntẹ́ni ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga olùkọ́ onípò kì-ín-ní, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ó jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn iṣẹ́ tí àwọn Olùkọ́ tí ó ń kẹ́kọ̀ọ́ gboyè ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ lórí ẹ̀kọ́ Ilé-Ẹ̀kọ́ Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ (B.Ed. Primary Education) ń ṣe ní ilé - ẹ̀kọ́ gíga Yunifásítì. Ohun tí ó fa èyí ni pé àwọn olùkọ́ èdè Yorùbá wọ́n bí imí eégún, èyí ni yóò sì jẹ́ kí a rí àwọn olùkọ́ tó láti lè kọ́ àwọn ọmọ ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú èdè àbínibí àti láti kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ẹ̀kọ́ girama ọlọ́dún mẹ́ta àkọ́kọ́ ní èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè kejì.

## Kí ni Ẹ̀kọ́.

"Ẹ̀kọ́ gbé ni níyì ọgbọ́n gbé ni ga gọ̀gọ̀rọ̀".
Ṣóbò Aróbíodu - Aláṣàrò - ọ̀rọ̀ ni ó sọ gbólóhùn òkè yìí nínú ewì rẹ̀ lórí pàtàkì ẹ̀kọ́. Ẹ̀kọ́ kò rọrùn láti fún ní oríkì nítorí pé onígba ojú ni. Ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ sí ẹdá láti ìgbà tí a bí i sáyé títí ó fi di ọjọ́ ikú ni. Ó jẹ́ ohun tí àwùjọ máa ń fi lé ẹnikọ̀ọ̀kan lọ́wọ́ kí o le mọ bí ìgbé ayé àwùjọ náà ti rí Chauhan (1978) sọ pé ẹ̀kọ́ jẹ́ ọ̀nà tí a ń gbà tọ́ tàbí kọ́ ènìyàn ní ìwà kí ó le mọ bí a á ti í gbé láàárín àwùjọ ní pẹ̀lẹ́kùtù.

Ẹ̀kọ́ tí a ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí ju èyí tí ènìyàn lọ kọ́ ní Yunifásítì lọ. Ó kọjá mo mọ̀-ọ́n kọ, mo mọ̀-ọ́n kà. Ẹ̀kọ́ tí a ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí jẹ́ àkójọpọ̀ ìrírí tí a ní ní inú ilé, ilé-ẹ̀kọ́, ilé ìsìn, báǹkì, ibùdókọ̀, ìrìnàjò, nínú oko, àní ní àwùjọ lápapọ̀. Ọ̀pọ̀ ẹ̀kọ́ ni a ń kọ́ láìmọ̀ tàbí láìfura. Arinze (1965) tilẹ̀ sọ pé ẹ̀kọ́ ni ìdàgbàsókè tí ó ń dé bá

ènìyàn nípa ti ẹ̀mí, tí ara, ti ọpọlọ ti ìfẹ́ inú ẹni, ti ìmọ̀lára ẹni, àti ìgbésí ayé ẹni náà lápapọ̀.

Ohun tí a pè ní ẹ̀kọ́ a máa yí ìwà ẹni padà nípa sísọ ọ̀pè ènìyàn di ọlọ́gbọ́n; nípa sísọ púrúǹtù di ọ̀mọ̀wé, àti sísọ ọ̀mọ̀wé di ọ̀jọ̀gbọ́n. Tí ọmọ kò bá mọ ìwée kà tàbí tí kò bá mọ ìwée kọ, tí a bá kọ́ ọ tí ó le kọ tí ó sì lè kà, ó ti kọ́ ẹ̀kọ́ nìyẹn.

Ní àwùjọ Yorùbá, ohun tí ó jẹ́ olúborí tàbí ẹ̀rọ̀ǹgbà gbogbo ẹ̀kọ́ ni kí ènìyàn jẹ́ ọmọlúwàbí. Láti jẹ́ ọmọlúwàbí ni kí ènìyàn jẹ́ oníwà rere nípa pé ó ń bọ̀wọ̀ fágbà, ó ń pa òfin ìlú mọ́, ó nífẹ̀ẹ́ ìlú rẹ̀ dénú, ó ń fi ọ̀wọ̀ fún àwọn òbí rẹ̀, ó jẹ́ olóòótọ́ lóde àti nínú ilé, ó sì tún ní ẹ̀mí ìrànlọ́wọ́ fún àwọn aláìní tàbí àwọn tí ó wà nínú ìṣòro àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí ó ti wù kí ènìyàn ní ìmọ̀ tó, bí kò bá fi ìwà kún un, irú ẹni bẹ́ẹ̀ kò lẹ́kọ̀ọ́ rárá. Àwọn Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ìwé kọ́ kọgbọ́n, àlejò ọkàn.

Kí ẹ̀kọ́ tó lè wáyé pàápàá jùlọ ní ilé - ẹ̀kọ́ ó gba pé kí olùkọ́ ó wà kí ó sì ṣe tán láti kọ́ akẹ́kọ̀ọ́; ó sì tún gbà pé kí akẹ́kọ̀ọ́ náà ó wà kí ó sì ṣe tán láti gba ìdánilẹ́kọ̀ọ́.

## ÈDÈ ÀTI Ẹ̀KỌ́

Bí ìgbín fà, ìkarahun a tẹ̀lé e. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ọ̀rọ̀ ẹ̀kọ́ àti èdè jẹ́. Èdè ni ohun èlò pàtàkì tí a ń lò láti kọ́ ọmọ ní ẹ̀kọ́. Èdè ni ọmọ fi ń ronú, èdè ni ó fi ń gbé èrò ọkàn rẹ̀ jáde bẹ́ẹ̀ náà ni olùkọ́ ń lò ní ilé-ẹ̀kọ́ láti kọ́ ọmọ. Ẹ̀kọ́ àti èdè sì dàbí apá méjì tí ẹyẹ fi ń fò. Okùn tí ó so ẹ̀kọ́ àti èdè pọ̀ yi púpọ̀. Láìsí èdè, yóò ṣòro fún ẹ̀dá láti kọ́ ẹ̀kọ́. yàtọ̀ sí pé a ń fi èdè ronú àti pé a ń fi gbé ìrònú wa jáde, èdè náà ni a fi ń mọ ìrò inú elòmíràn - ó lè jẹ́ nípa ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀ tàbí ohun tí ó fi ọwọ́ ara rẹ̀ kọ sí inú ìwé. Ṣe a kì í gbé inú ọlọ́rọ̀ mọ ọ́n.



Bí a kò bá ní kóyán èdè kéré ó yẹ kí a mọ̀ pé èdè ló ṣe pàtàkì jù nínú ẹ̀kọ́ kíkọ́ àti kíkọ́ni nítorí pé bí olùkọ́ bá ṣe gbọ́ èdè tó ni yóò ṣe lè lò ó láti ṣe àlàyé ọ̀rọ̀ tàbí iṣẹ́ fún ọmọ dé ibi òkooro - jáko. Bí akẹ́kọ̀ọ́ bá sì fi gbọ́ èdè tó ni yóò ti ṣe mọ̀wé tàbí lóye tó.

Ó ṣe é ṣe kí a máa bèèrè pé irú èdè wo ni ó dára jù tí a lè fi kọ́ ọmọ. Èdè àbínibí ni ó tọ̀nà tàbí dára jù láti fi kọ́ ọmọ lẹ́kọ̀ọ́. Èdè àbínibí ni ọmọ fi ń ronú nítorí ìdí èyí, ẹ̀kọ́ yóò le yé ọmọ dunjú-dunjú àti jinlẹ̀ - jinlẹ̀ bí a bá fi èdè àbínibí kọ́ ọ.

Ẹ̀kọ́ tí a kọ́ ni èdè àjèjì kì í tètè yé ni. Fífi èdè àjèjì kọ́ ọmọ lẹ́kọ̀ọ́ kì í sábàà so eso rere fún àwùjọ. Ọ̀pọ̀ akẹ́kọ̀ọ́ tí ó jáde ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ló wà tí wọn kò mọ ọ́n kọ tàbí mọ ọ́n kà ní èdè Yorùbá tàbí ti Gẹ̀ẹ́sì nítorí pé èdè àbínibí (Yorùbá) tí ó yẹ kí olùkọ́ lò, kò lò ó, èdè Gẹ̀ẹ́sì tí a sì fi ń kọ́ wọn, kò yé olùkọ́ mìíràn gan an bẹ̀lẹ̀ǹtàsé ẹni tí ó ń kọ́.

Ọ̀pọ̀ ìwádìí ìjìnlẹ̀ ti fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé èdè àbínibí ni ó dára jù láti kọ́ ọmọ ní ẹ̀kọ́. Pàtàkì nínú iṣẹ́ ìwádìí bẹ́ẹ̀ ni èyí tí ọ̀jọ̀gbọ́n Babátúndé Fáfúnwá ṣe agbátẹrù rẹ̀ ní Yunifásítì Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ ní Ilé - Ifẹ̀ èyí tí ó wáyé ní ilé ẹ̀kọ́ St. Stephen Primary School, Modákẹ́kẹ́, Ilé - Ifẹ̀ nínú èyí tí a ti pín àwọn akẹ́kọ̀ọ́ sí ipa méjì. Àwọn ti ìpín kì-ín-ní ni àwọn tí a fi èdè àbínibí kọ́ ní gbogbo iṣẹ́ àyàfi èdè Gẹ̀ẹ́sì tí wọ́n kọ́ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ kan pàtó. Àwọn tí a pín sí ìpín kejì ni a sì fi èdè Gẹ̀ẹ́sì àti Yorùbá kọ ní gbogbo iṣẹ́. Àbájáde ìwádìí yìí fi hàn pé àwọn tí a fi èdè àbínibí kọ́ ní gbogbo iṣẹ́ (àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti ìpín kì-ín-ní) ni wọ́n ṣe dáradára ju àwọn ti ìpín kejì lọ, kódà wọ́n tún ṣe dáradára nínú èdè Gẹ̀ẹ́sì. Ẹ̀kọ́ èdè àbínibí níhìn-ín kò pagi-dínà ẹ̀kọ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì rárá nítorí pé àwọn olùkọ́ ti o ní ìmọ̀ ẹ̀kọ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì dunjú-dunjú ni ó kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ (pàápàá jùlọ) ti ìpín kì-ín-ní.

Ọmọ tí a bá fi èdè àbínibí kọ́ yóò lè máa kópa nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú kíláàsì nítorí pé ẹ̀kọ́ ń yé e, èyí yóò sì mú kí òye rẹ̀ ó gbòòrò nínú ohun tí ó ń kọ́. Ọmọ tí a kò fi èdè abínibí kọ́ lọ́pọ̀ ìgbà yóò kàn máa wò gbùn ùn bí orí ẹran ni nítorí pé gbogbo ohun tí olùkọ́ ń sọ ni yóò dàbí àdììtú lójú rẹ̀.

Síwájú sí i, ọmọ tí a fi èdè àbínibí kọ́, dandan ni kí ohun tí ó kà tàbí tí ó bá ń gbọ́ ó tètè máa yé e, òun náà yóò lè lo èdè yìí ní ọ̀nà tí ó gbé oúnjẹ fẹ́gbẹ́ tí ó sì tún gbàwo bọ̀. Nípa báyìí ni ọmọ lè fi gbé àṣà wa lárugẹ. Nípa báyìí ni yóò lè mú ìdàgbàsókè bá orílẹ̀ - èdè nígbà tí ó bá fi èdè tí ó yé e ṣe iṣẹ́ ìwádìí.

Ta Ni Olùkọ́ Èdè (Yorùbá).

Kí a tó lè pe ẹnikan ní olùkọ́ èdè ó yẹ kí a mọ̀ bóyá irúfẹ́ ènìyàn bẹ́ẹ̀ mọ èdè náà dunjúdunjú. Ó yẹ kí a mọ̀ bóyá ṣe ni a fún un ní èdè náà kọ́ nítorí pé o lè sọ ni tàbí ó kọ́ ẹ̀kọ́ gboyè lórí èdè náà. Nígbà tí a bá ní kí ènìyàn kan ó kọ́ èdè Yorùbá láìní ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ nínú èdè náà, bí ìgbà tí ènìyàn fi ajá silẹ̀ tí ó ń fi àgùntàn dẹ ìgbẹ ni. Ó ṣe pàtàkì kí Olùkọ́ ó ní ìmọ̀ tí ó jinlẹ̀ nípa èdè kí ó sì tún ní ìmọ̀ nípa ọgbọ́n ìkọ́nilédè kí ó tó lè pegedé gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ èdè.

Olùkọ́ èdè gbọ́dọ̀ mọ̀ nípa àṣà èdè tí ó ń kọ́ nítorí pé àṣà àti èdè kò ṣe é pín níyà. Ìṣesí, ọ̀rọ̀ ẹnu, ìhùwàsí àwọn ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan ni ó jẹ́ kí a mọ̀ wọ́n yàtọ̀ gẹ́gẹ́ bí Yorùbá, Ìgbò àti Hausa.

Olùkọ́ èdè ni ó máa ṣe ètò kíkọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Ó gbọ́dọ̀ ṣe ètò àwọn ohun èlò amẹ́kọ̀ọ́yémọ àti irúfẹ́ ọgbọ́n ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí yóò lò láti kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní àkọ́yege.



Olùkọ́ èdè gbọ́dọ̀ mọ ojú orí àwọn akẹ́kọ̀ọ́, irú ilé tí wọ́n ti wá, (bóyá ìdílé ọlọ́rọ̀ / tálákà, ọ̀mọ̀wé / púrúntù, ìdílé tí wọ́n ti ń sọ Yorùbá tàbí Gẹ̀ẹ́sì).

Olùkọ́ gbọ́dọ̀ máa yẹ iṣẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ wò lóòrèkóòrè kí ó sì máa tọpinpin ìhùwàsí akẹ́kọ̀ọ́ láti àti tí ṣé pé akẹ́kọ̀ọ́ hu ìwà ọmọlúàbí.

Olùkọ́ èdè (Yorùbá) gbọ́dọ̀ máa lọ́wọ́ sí ìdàgbàsókè. Kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù àti àyípadà tí ó ń dé bá a; èyí ni yóò jẹ́ kí ó mọ ìṣòro tí ó ń dojú kọ iṣẹ́ rẹ̀ yóò sì le gba àwọn aláṣẹ ní ìmọ̀ràn láti ṣe àtúnṣe àti àyípadà tí ó tọ́.

Ó yẹ kí Olùkọ́ èdè Yorùbá máa lọ sí gbogbo ìpàdé Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè Ìjìnlẹ̀ Yorùbá. Ó gbọ́dọ̀ gbọ́ èdè yìí ágbọyé, kí ó sì mú un bí iṣẹ́ òòjọ́ rẹ̀. Kò gbọdọ̀ fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú un rara.

Olùkọ́ gbọ́dọ̀ gbaradì fún iṣẹ́ tí ó fẹ́ ẹ́ kọ́. Ó gbọ́dọ̀ jẹ ẹni tí ó lè ronú kíákíá, kí o sì máa gba ìmọ̀ràn ẹlòmíràn mọ́ tirẹ̀, ó gbọ́dọ̀ máa gbé iṣẹ́ rẹ̀ kalẹ̀ bí ẹni tí ó ní òye kíkún nínú iṣẹ́ náà, ẹni tí ó lè fi sùúrù ṣe àlàyé ọ̀rọ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pẹ̀lú àpẹẹrẹ láti mú kí èròngbà rẹ̀ kẹ́ṣẹ járí.